**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**OLÚWA, ṢE MÍ NÍ ÀDÌTÚ ÀRÀ**
**OṢÙ KEJE, ỌDÚN 2024**
Ìwé Mímọ́ Kíkà: 2 Àwọn Ọba 2
Ìjẹ́wọ́: Éksódù 14:15

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá Ìfẹ́, rànmílọ́wọ́ láti farabalẹ̀ láti tẹ́tí gbọ́ ohun gbogbo tí O ní láti sọ, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá mi, gbàmí kí n má bá a sinmi púpọ́ jù sí àwọn ọ̀nà àti èrò mi, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá mi, gbàmí kí n má bá a fojú tẹ́mbẹ́lú mú ọ̀rọ̀ Rẹ tàbí sẹ́ ìpè Rẹ, ní orúkọ Jésù.
8. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, jó gbogbo irúgbìn òkùnkùn nínú ọkàn mi di éérú, ní orúkọ Jésù.
9. Mo gba ìfọwọ́kàn ọ̀tun láti ọ̀run, ní orúkọ Jésù.
10. Bàbá mi, tan ìmọ́lẹ̀ iná ọ̀tun sínú ọkàn, ní orúkọ Jésù.
11. Ọlọ́run olóre-ọ̀fẹ́, rànmílọ́wọ́ láti lo àkokò tí a fifún mi ní ọ̀nà tí ó ma mú èrè wá, ní orúkọ Jésù.

12. Èmi yóò súnmọ́ Ọ si nípa níní òye ìwà ìṣẹ̀dá Rẹ sí i, ní orúkọ Jésù.
13. Ọlọ́run Ìyanu, àwámárìdí àti àìlópin, ṣàánú fún mi, ní orúkọ Jésù.
14. Olúwa, ṣàánú fún mi, kí O sì fọ̀ mí mọ́ kúrò nínú gbogbo àìlera mi, ní orúkọ Jésù.
15. Bàbá, dáríjì mí fún gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ búburú àti àwọn ìgbésẹ̀ tí mo gbé láì ronújinlẹ̀, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, jẹ́ kí agbára láti gbọ́nràn sí Ọ lẹ́nu pátápátá, àti láti gbé ní ọ̀nà Rẹ bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
17. Bàbá, túmisílẹ̀ kí n má ba à mọ̀ Ọ́ lámọ̀jù, ní orúkọ Jésù.
18. Bàbá mi, kọ́ mi ní agbára àdúrà, ní orúkọ Jésù.
19. Bàbá mi, kọ́ mi ní àwọn ibùkún àdúrà, ní orúkọ Jésù.
20. Bàbá mi, kọ́ mi ní áísìkí àdúrà, ní orúkọ Jésù.
21. Olúwa, fí ọwọ́ ìfẹ́ Rẹ kàn mí, kí O sì yímipàdà nípa ore-ọ̀fẹ́ Rẹ, ní orúkọ Jésù.
22. Ìwọ agbára ìfọ́jú t'ẹ̀mí, kú, ní orúkọ Jésù.
23. Gbogbo agbára tí ó fẹ́ kí n ran àwọn ọ̀tá mi lọ́wọ́ láti pamírun, àrá Ọlọ́run, ṣekú pa wọ́n, ní orúkọ Jésù.
24. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, ṣí aṣọ lójú gbogbo ìránṣẹ́ òkùnkùn tí ó dagọ̀ bojú láti yọ ọ̀rọ̀ mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo ọ̀tá tó n pinnu láti wá sínú ayé mi láti ba tèmi jẹ́, Ọlọ́run dìde, jó wọn run, ní orúkọ Jésù.
26. Ọ̀tá mi tí ó kàn láti gbógun tì mí, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
27. Olúwa, bí mo bá jẹ́ ọ̀tá ara mi, dìde kí O rànmílọ́wọ́ lónì, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo agbára tó n gbin àwọn àmì búburú sínú ayé mi láti pamí, kú, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo agbára tó fi ọkọ̀ ayànmọ́ mi sínú ìgbèkùn, ya wèrè, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
30. Agbára tó n gbógun tì mí ní kólekolé si bí mo ṣe n gbàdúrà ní kíkankíkan, iná Ọlọ́run, jó wọn run, ní orúkọ Jésù.
31. Ọ̀sì pọ́nbẹ́lẹ́ tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi, kú, ní orúkọ Jésù.

32. Gbogbo agbára tó n kó àbọ̀dè ibi bá orúkọ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
33. Àwọn agbára tó n tan àbẹ́là ibi lòdì sí ògo mi, jóná pẹ̀lú àbẹ́là rẹ, ní orúkọ Jésù.
34. Agbára àjèjì ìyówù tó n ta ẹ̀jẹ̀ sílẹ̀ nítorí mi, kí àṣírí rẹ tú, kí o sì gba ìtìjú, ní orúkọ Jésù.
35. Olúwa, jẹ́ kí aṣọ àwọn ọ̀tá mi bẹ̀rẹ̀ siní run òórùn ìkórìra, ní orúkọ Jésù.
36. Ọlọ́run dìde, tú ẹ̀rù àjèjì jáde sórí àwọn ọ̀tá mi kí wọ́n lè dápadà ohun tí wọ́n ti jí mọ́ mi lọ́wọ́, ní orúkọ Jésù.
37. Idà tí àwọn ọ̀tá mi gbẹ́kẹ̀ wọn lé yóò pa wọ́n run lójijì, ní orúkọ Jésù.
38. Olúwa, jẹ́ kí ikú jẹ àwọn àgbà ìkà tó n fimí re, ní orúkọ Jésù.
39. Gbogbo ọfà àdánù nlá tí wọ́n rán lòdì sí mi láti pamílẹ́kún, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
40. Àwọn ọfà tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n ṣe aṣìṣe tíkò látùnṣe, tapadà, ní orúkọ Jésù.